Alujanna súnmọ́ ìkọ̀ọ̀kan nínú yín ju okùn bàtà rẹ lọ, Iná naa sì rí bẹ́ẹ̀

Lati ọdọ ọmọ Mas'ud - ki Ọlọhun yọnu si i - ó sọ pé: Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a - sọ pé: "Alujanna súnmọ́ ìkọ̀ọ̀kan nínú yín ju okùn bàtà rẹ lọ, Iná naa sì rí bẹ́ẹ̀".

[O ni alaafia] [Bukhaariy gba a wa]

Anabi - ki ikẹ ati ọla Ọlọhun maa ba a – fún wa niroo pé Alujanna ati Ina súnmọ́ ènìyàn gẹgẹ bi okùn bàtà tó máa n wà lókè ẹsẹ̀ ẹ súnmọ́, nitori pé ó ṣee ṣe kí eniyan ṣe iṣẹ ijọsin kan, kí iṣẹ yii sì mu un rí iyọnu Ọlọhun, yoo sì mu un wọ Alujanna, ó sì ṣee ṣe kó dá ẹṣẹ kan, kí ẹ̀ṣẹ̀ yii sì jẹ okunfa fun un tí yoo fi wọ Ina.

http://sunnah.global/hadeeth/yo/show/3581